**Ọrọ agba**

ỌPẸKẸKẸTẸ ndagba, iru adamọ mbajẹ. Otitọ d'ọ'a o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

Irohin Yoruba

NO. 116 WEDNESDAY JULY 15 – TUESDAY JULY 21 1964 KOBO MẸTA 3D

**AKIYESI**

Ka oro egbe Afenifere lekunrere loti esun pe awon en'se ibi kan ngbero lati fi majele si onje fun Oloye Ọbafemi Awo'owo, babasale egbe Afenifere ti o wa logba 'ewon bayi. Ọro egbe Afenifere na koyoyo.

Mavalai ra IROHIN YORUBA ni ose ti o mbo.

## Ori ki ifọ ahun, ẹdọ ki irin igbin:

# ỌRỌ AWO DI ỌRUN IJỌBA BALEWA




'Ọgẹdẹ nra, nwọn ni o npọn ni'

KO pẹ pupọ si igbati ile ẹjọ ganran ni Eko ti kọ ẹjọ kotẹmilọrun ti Oloye Awolọwọ pe si ile ẹjọ na ti awọn asiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre ti bẹrẹ si gbọ finfin pe nwọn magbe Oloye Awolọwọ kuro ni ọgba ẹwọn ti Eko lọ si ọgba ẹwọn miran ni orilẹede yi; eyiti yio fun awọn oluṣebi laye lati le ta jamba fun Oloye Awolọwọ nipa fifun un ni majele jẹ.

Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti Naijiria si ti kọ iwe kan si Olotu Ijọba Apapọ, Alhaji Abubakar ni nkan bi ọjọ mọkanla sẹhin lati sọ ẹdun ọkan ẹgbẹ na nipa ọrọ na ti nwọn ngbọ kiri pe awọn kan fẹ fun Oloye Awolọwọ logun jẹ.

Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti tun kọ iwe keji ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi lori ọrọ kanna ti nwọn ngbọ kakiri.

Ninu iwe akọkọ ti ẹgbẹ na kọ si Olotu Ijọba Apapọ ki o to lọ si ile Gẹẹsi; Alhaji Adegbenro, adele



OLOYE AWOLỌWỌ

babasalẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre kesi Olotu Ijọba Apapọ lati lo gbogbo agbara rẹ lati dabobo ẹmi Oloye Awolọwọ nitoripe on ti nhu gbọ pe awọn ẹni ibi ti nwa ọna lati paa. Nwọn si fi ẹda iwe na ti

(Wo oju ewe kejo)

## Ajọṣepọ Ọlọpẹ, Alakukọ daraba

DOKITA Michael Okpara, Olotu Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun ati babasalẹ ẹgbẹ Alakukọ ṣe kilọkilọ ni ibi ipade ẹyẹ kan ti ẹgbẹ Alakukọ fi gba lalejo ni Aba ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kejọ osu yi fun ipari irin-ajo ọsẹ mẹjọ ti o se kakiri Ipinlẹ Ila-Orun laipẹ yi pe abuku ati ẹtẹ ni yio jẹ fun ẹnikẹni ninu awon omo ẹgbẹ on ti o ba lodi si ajumoṣepọ ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Dokita Okpara se ikede ajumosepo na, o si fi kun pe ajumosepo na ti di oro imule larin egbe on ati egbe Afenifere gege bi ibamu pelu ipinnu ti egbe on se ninu ipade alabesekele egbe na ti nwon se ni ilu Benin laipe yi.

IPINYA

Dokita Okpara so siwaju si pe lati ojo ti on ati adele babasale egbe Afenifere ti bere eto ajumosepo na ni ile Babasale egbe Afenifere, Oloye Awolowo, niOke Ado ni Ibadan ni ipinya ati iyapa ti wa larin awon ti o fe ilesiwaju ati awon jeunjeun oselu, o wa se alaye pe enikeni ti o ba lodi si ajumosepo na nilati fi egbe

Wo oju ewe kejọ

## Ẹgbẹ Akintọla pinnu lati sọ ipinlẹ Yoruba di 'ọrun apadi'

ẸGBẸ Afẹnifẹre kede ni ọjọ kẹwa oṣu yi ni Ibadan pe ẹgbẹ NNDP ti pinnu lati sọ Ipinlẹ Iwọ-Orun sinu rudurudu ati rogbodiyan nipa tita jamba fun awọn alatilẹhin ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ.

Ẹgbẹ Afẹnifẹre tu aṣiri jamba na ninu iwe kan ti ẹgbẹ na kọ si oga awọn ọlọpa ni ipinlẹ Iwọ-Orun.

Ẹgbẹ na sọ pe ẹgbẹ NNDP ti fi orukọ ati nọmba mọto awọn aṣiwaju ẹgbẹ Alakukọ ati Afẹnifẹre mẹrinlelọgọfa fun awọn janduku ẹgbẹ Dọmọnu lati gbẹmi wọn ati lati ba mọto wọn jẹ bamubamu. Ẹgbẹ Afẹnifẹre sọ wipe eyi jẹ ọkan ninu eto iparun ẹgbẹ NNDP ti nwọn pe oruko rẹ ni ILANA IPARUN.

Ẹgbẹ Afẹnifẹre tu aṣiri wipe ile okan ninu awọn aṣiwaju ẹgbẹ NNDP ni Ibadan ni ẹgbẹ na ti ṣe ipinnu iparun na ni ojo keji oṣu yi.

Ninu iwe kan ti nwon fi ranṣẹ si oga awọn ọlọpa ni Ipinlẹ Iwọ-Orun, Ọgbẹni E. Glaisher ni Ibadan, ẹgbẹ

(Wo oju ewe kejo)

## Digbolugi Dọmọnu kọlu Akinyẹmi

Ni ojo kesan osu keje odun yi ni awon janduku egbe oselu kan lo dana ti nwon si sa omo egbe Afenifere kan ni Ile Igbimo Asofin Apapo, ti o tun je oga ile e o giga 'Ilesha Grammar School', Eniowo J. A. Akinyemi logbe yannayanna, ti nwon si ko owo ati awon ohun ti o wa lowo ati inu oko re sa wo igbo pata.

Eniowo J. A. Akinyemi npada lati Ibadan lo si Ilesha lehin ti o kuro ni ile iwosan nla ti Unifasiti Ibadan nibiti o ti wa fun itoju ara re fun igba die nigbati awon janduku na dana re ni Ikire, ilu kan ti o je iwon ibuso merinlelogun si Ibadan larin Ibadan si Ilesha ni oro ojo buburu yi.

Eniowo J. A. Akinyemi ti wa ni ile Iwosan ti Ijo eleto 'Westey Guild Hospital' ni Ilesha nibiti nwon ti nse itoju re lowo bayi. Bakanna ni dereba re se fara gba ogbe, on na si wa ni ile iwosan kan na nibiti nwon ti nse itoju re.

Awon olutoju ile iwosan na fi ye onirohin wa pe ogbe Eniowo Akinyemi po pupo ati pe emi re wa lowo ewu.

Irohin tun fi han pe awon janduku na fi ake kan sa Eniowo Akinyemi nigbati won ba ti nwon fi sile tan ni nwon ba fi oko di ona ti nwon fi ri aye se on ati dereba re lore.

## ADELE YAMUTU

Oba Adeniji Adele ọba Eko fi lẹ se ayo bora ni ọjọ Aiku ti Iṣe ojọ kejila oṣu keje ọdun yi Ẹni adọrin ọdun ni ise

O di oba Eko ni ojo kini osu kewa odun 1949, on ni o se ikokanlelogun ninu awon oba ti o ti waja ni ilu Eko, o gba oye K. B. E ni odun 1962.

Ọba Adele je ara awon eniti o fi owo ara re fa ara re kale lati ran Naijiria lowo ninu ogun 1914.

Edeaiyede be sile nigbati o joba larin on pelu Omo-ba Oyekan eniti on paapo ndu ipo oba. Ọro na gba to odun mejo ki o to pari lati inu ile ejo giga Kotemilorun ni ilu Oyinbo nibiti awon adajo tun gbe da Oba Adele lare.



